**Wanted Urgently**

2 Advanced Apprentice and 4 Apprentice Printers
Apply to
Adaranijo Printing Press
10, Andrew St. Lagos
Phone: 23636

**IROHIN IMOLE**

MOTTO: IMOLE DE, OKUNKUN PARADA.

**AKIYESI**

Ki enikeni ti oba fe ra Iwe Irohin Imole ni Abeokuta ma lo ra lodo Asoju wa
Ogbeni Francis Ogundimu
6, Ake Street,
Abeokuta.

VOL. III No. 125 MONDAY NOVEMBER 23 — NOVEMBER 29 1959 KOBO KAN (1d)

# Opolopo awon Dokita nlo ri Adajo Agba

EKO. Awon dokita ti o nsise funrawon ti won ko si ni abe Ijoba yio lo ri adajo agba Alagba Adetokubo Ademola lati ba roro lori oro adajo ti ile ejo kerere (Magistrate Court).

ti o ni ki won lo gbe alaisan kan lati ile-iwosan ni Yaba lo si ile-iwosan ni eko (General Hospital)fun atunyewo. Alaisan yi G. F. Opara ti o je okan ninu awon omo ile igbimo Munisipa Eko, ni o nilati fi ara han niwaju adajo yi bi odaran ninu oro esun peo lu Oga Olopa kan, sugbon ko le wa si Kotu nitori ara re ko da, o si wa ni ile iwosan Yaba yi.

Won se atako si wipe ko dara lati gbe alaisan opara yi lati ile iwosan Yaba ti o wa lo si ile iwosan ti Ijoba (General Hospital), won sise atikun pe oye ki Dokita Ijoba lo wo alaisan yi ni ile iwosan ti o wa ni, pe ki se on eto rara lati gbe alaisan yi lo si ile iwosan Ijoba won wa ni eleyi le da nkan miran ti kodara sile,

Ni ipade ti awon Dokita se ni ile egbe Island Club ni ojo Jimoh ni won so wipe oje nkan ti oje awon lokan pupo, ti o si dun won pe bi o ti je awon fe jeki ore wa ni arin awon pelu awon adajo.

## Adajo se Ikilo fun awon Odomobirin pe ki won ye ja awon Odomokunrin lole

Adajo agba ni ile idajo ibile Ilesha (Grade 'B' Customary Court) Ogbeni C. A. Fajemisin ro ni ile idajo re pe on ko ni gba awon odomobirin ma ja awon odomokunrin ni ole nipa pe ki won ma tan won je pe awon yio fe won.

Adajo Fajemisin so oro yi nigbati o ngbo esun ti Muniratu Abegbe fi sun Emanuel Olasupo pe ki ile idajo tu igbeyawo awon ti o sun mo ka. Nigbati adajo Fajemisin wo Abegbe koko, o so pe ejo ko gba pe ki enyin Wundia ma ja awon apon ni ole, ki o si ja ajabo re. O dabi eni wipe o ti ba awon obi re di i lati gba owo lowo okunrin yi ni.

Muniratu ti o ti san ponun mewa si ile ejo tele fun owo ana ti Emanuel se le lori ni adajo so wipe ki o san Adota poun imi si ile ejo nigbati Emanuel ni ponun metadilogoji ati sile medogun ni on ti na lori Muniratu.

Ogbeni Fayemisin se ikilo fun Muni wipe a fi ti o ba san owo yi nikan ni on le gbo nkan-ki-kan ti o ba fe so, won si sun ijo ejo na si ojo ketadilogbon osu December.

## Ha! eti re melo?



Eyi yi ni Ero Alata todaraju gbogbo eyi ti won ti nlo telerilo leyin ata lilo o tun le lo Igbado ati Oka Baba ati Ewa - ere orisirisi.

**£45 Ni a nta** Pelu Enjinni Petrol tabi ati pelu Eletiriki Muto.

O WA NI SOBU:-

**Akoshile Brothers,**
5, Balogun Street West,
P. O. Box 599.
Phone No., 24395. LAGOS.

## MOGBAYI BABY MIXTURE

OLURANLOWO FUN AWON ABIYAMO




MOGBAYI BABY MIXTURE je ogun pataki ta se ni Asepe fun Awon omode, ati nlo ogun yi fun opolopo odun sehin pelu idaniloju fun Awon ise ribiribi ti o ti nse. MOGBAYI BABY MIXTURE je egbogi to dara pupo fun igbona iko, orutu Aiperi, Osi inu omode, jedi jedi Kokoro ori omode. O dara fun omode ti ko tete rin ati fun awon sisan mitan bebe lo. O amu ki omode ma nsun fonfon, o amu ki ehin hihu je iro run fun awon omode. osi njeki awon omode tobi, osi nmu won dan ni awo. Enyin Abiyamo, eku fojuba egbogi yi. Aran yin leti pe MOGBAYI BABY MIXTURE je egbogi ti ko se mani fun awon omode. Ijafara lewu pupo, tete lo ra ti eni ile itaja Egbogi towa ni Adugbo re.

Igo kekere re je 2/6d Igo nla je 4/6d
LILO RE:- Sibi kekere kan lemeta lojumo

*Wholesale Distributors*
A. K. KARIMU ANJOLA & BROTHERS

6, Balogun Street West, Lagos Nigeria. Phone 22515

34, Docemo Street, Lagos. Phone 24247

# IMOLE

EṢIN ỌKỌ WA-
IMỌLẸ DE OKUNKUN
PARADA
*Editorial Works & Office*
16, Bamgbose Street,
Lagos.
Telephone:- 21985
United Kingdom Representative
Publishing Distributing
177, Regent Street,


## Ẹnyin osise, E so owo po

O jẹ on ti o ya ni lẹnu lati ri wipe, lati ọjọ kan yi wa, awọn oṣiṣẹ orilẹ ede wa ko tile fi ẹnu ṣe ọkan, lati gbe ẹgbẹ ti yio ma fi ọrọ won ṣe ọkan jọ. Ko si ohun ti o fa eleyi ju pe, ijẹkujẹ ati igbakugba lati ilu okere, ti o ti di asa awọn olori ẹgbẹ osisẹ lo jẹki ọrọ di rudurudu bayi, kiṣe awọn olori ẹgbẹ oṣiṣẹ nikan lo jẹbi ọrọ ijẹkujẹ yi, ṣugbọn awọn oṣelu paapa li a ri bawi, awọn na, ọwọ wọn komọ.

Ki ṣe awọn oṣelu ni a mbawi ninu ọrọ wa ti ọse yi bikoṣe awọn oṣiṣẹ. O yẹ ki ẹnyin oṣiṣẹ sun ikaka, ki ẹ ro ori, ki ẹ mọ wipe Naijiria titun lo mbọ yi, kini tiwa yio ti jẹ ninu rẹ? Iru anfani wo la wa gẹgẹbi oṣiṣẹ yio ni, ni ọjọ iwaju? Kini aye ati ipo wo ni a o wa ninu Naijiria titun?.

Awa oniwe "IROHIN IMỌLE" yio sa gbogbo agbara lati dahun diẹ ninu ibere nwọnyi gẹgẹbi lakaye ati ọgbọn wa ti to. Awa si to pe ẹ o kọ ọgbọn diẹ ninu omugọ ti wa. Ikini, ẹ jẹki a mu tan ara wa jẹ, awọn oyinba ni o npa ni owe wipe bi ẹnikan ko ba fun fẹre tirẹ, ko le ri ẹni bẹ on fun u. Bẹ gẹgẹ ni wipe, ti ẹnyin oṣiṣẹ ko ba pe ara nyin ni enia ni ... Naijiria titun tọ mbọ, ... ti yio pe nyin ni ... owọ nyin ni ẹmi ... yi wa. Awa fi nye nyin wipe ẹ nilati pe awọn olori nyin jọ ki ẹ fi ọrọ gun won ninu, ki won ye fakuraba ṣe, ki wọn lọ mọ onun ti wọn nṣe. Gẹgẹbi oye ti wa, ẹgbẹ oṣiṣẹ ko gbọdọ fi ara mọ ẹgbẹ oselu kankan rara, aye ti ẹgbẹ oṣiṣẹ ọtọ ti oṣelu ọtọ. Niwọn igbati ẹ ba si nfi ara mọ ẹgbẹ oṣelu kan a bi ti ẹ ngbe ọkan si ekeji ewu nla ni o wa fun yin.

## Imoran nipa IFE

### IBERE

Ọkọ meji ni o nfẹ mi papọ lẹkanṣoso, oko si jẹ ki ọrọ yi han si awọn mejeji, awọn mejeji ni o si nba mi lopọ lasiko yi, ṣugbọn ko si han si ẹnikẹni ninu wọn. Nisisiyi, mo wa loyun, ekini nsope on lo ni oyun, ekiji papa nyọ ṣẹnkẹn pe iyawo fẹ to bimọ. Jọwọ Bọsẹde tani o yẹ ki ngbe oyun yi fun. Emi ni Aṣake T. Lagos.

### IDAHUN

Aṣakẹ T. Lagos— Ọrọ yi wa su mi pelu, ohun ti WO OJU EWE KETA

WO OJU EWE KETA


## Iwe Ilana Ifa, Erindinlogun, Iyanrin tite, Iwosan ati etutu sise pelu Egbogi Ajebidan

Ha! eti rẹ melo? Ogbokangi Babalwo ni o ṣeṣẹ se iwe yi fun lilo ati fun anfani gbogbo enia, ohun ti o wa ninu iwe yi ni () Ayajọ ti o daju hanrun, (2) Yanrin tite, (3) Egbogi Ajẹbidan, (4) Eyonu awọn agba (5) Awure wibẹ, jẹbẹ, (6) Etutu iwasẹ Ajẹbidan, (7) Ojulowo iwe Ifa ni iṣẹ. Babalawo tabi awọn ti o ba fẹ kọ Ifa nilati ni Iwe yi lọwọ, bi o ba ni iwe yi lọwọ, awọn Ọta, Ẹlẹiyẹ, Alapeta, Apeniapa. Adahunse Ologun, Babalawo ati awọn enia majẹki tẹni sunwọn ko ni lagbara lori rẹ.

IYE OWO
10/6d ẹyọ kan, £3 mefa, £5 : 0/- Dọsini.

## Turari Ajebidan

Turari yi tun lagbara bakanna lori awọn Ẹlẹiye, nipa lilo rẹ, o ko ni ... sita ọja, agbana ko si ni wọ inu igba rẹ, o le lo fun adura Tetedamilehun, Ako jalugbẹ ni fun awọn Emi okunkun, ni kukuru, Gbogb ... ni Turari yi, danwo

IYE OWO
10/6d Pangolo, 5/6d Idaji 3/- Idamẹrin 1/- Idarun
Iwe Itumọ Ala 2/6d, Gbedegbẹyọ Hausa 2/6d, Certificate of service 5/6d ẹyọ kan.

FI OWO RANSE SI:- J. O. SHOYINKA,
6, Ojo Road, Oduabore Mushin.






Eto ẹkọ ti Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun ṣe fun awọn agba, l'ọkunrin l'obirin, ti ko lọ ẹkọ tan ni ile-ẹkọ [illegible] ti kọ mọ, l'aye lati ṣe atunṣe nipa ẹkọ wọn. Ijọba nṣe iranlọwọ fun wọn lati le ka ati lati kọ [illegible] ki awọn bale ṣe ipa ti wọn [illegible] ilọsiwaju ti ... ati ti igbadun awọn enia. Ijọba ... fun awọn ... ati ... awọn iwe Yoruba ati ti ede ... Ijọba Ipinlẹ tun nfun awọn Ijọba Ibilẹ ni owo ... fun awọn ti nṣe eto ẹkọ awọn agba ti Ọga Ile Iṣẹ eto ẹkọ ... Ijọba si nṣe iranlọwọ bakanna fun Ile Ikawe ni fifẹ ati ... iwe irohin nibẹ.

Owo ti Ijọba fi silẹ fun iṣẹ ẹkọ awọn agba ni ọdun 1955 si 1956 jẹ ẹdẹgbẹfa poun, ti 1956 si 1957 jẹ ẹgbawa ... ogun. Iye kanna ni Ijọba na ninu ọdun 1957 si 1958.

Larin ọdun mẹta ... awọn agba to f'oruko silẹ fun ẹkọ yi jẹ ọkẹ marun ... ẹgbawa ati ọdunrun o din mẹtadilogun ni ọdun 1955 awọn ti nwọn fi oruko silẹ jẹ ẹdẹgbafa ni ọdun 1956 ọkẹ meji abọ, ni ọdun 1957 ọkẹ meji o le ẹdẹgbeje o din mẹdogun.

Ile Iṣẹ ti nkede Iṣẹ Ijọba Iwọ Orun Naijiria l'ogbe ọrọ yi jade.

O BERE LATI OJU EWE KEJI

mo mo rope o le se ni pe ki o tete fi ija ajakudoro-fun ọkan ninu awọn mejeji yi, ti won ba pari re maşe gbe, ti o ba bimọ tan, ki o ko lọ eyiti o feran ju lo, nigbati ẹ ba fa ti o ba di ọro Ijọba, ti Doctor ba se ayewo ẹ i ẹ ọmọ titun, iwọ ati awọn ọkunrin mejeji yio mọ ẹniti o ni ọmọ.

Şugbọn Aşakẹ T. mo gba ni iyanju nitori ki o le lo ẹmi re pẹ. Şọta nipa iwa buburu yi, nitori pe bibẹni lori ko jina si iru aşakaşa bayi. Emi ni B - sẹde 6, Ojo Road, Oduabọrẹ Mushin

## FEDERAL ELECTIONS 1959

NOMINATED OF CANDIDATES

Attention is drawn to the fact that under the Electoral Regulations as amended CANDIDATES ONCE NOMINATED CANNOT WITHDRAW.

R. E. WRAITH
Chief Electoral Commission

ALL EMINENT DOCTORS AND CHEMISTS IN NIGERIA KNOW:—

## "FERRO-HEPATINE"

The real physiological tonic for all. Extremely useful in all affections of the Nerves, Blood and vigour. Specially recommended in cases of Anaemia, Chlorosis, loss of strength, parasitic diseases, such as malaria, troublesome fevers impurities of the skin, particularly of the complexion, diseases of the bones and teeth, occasional beating as a result of long illness or insufficient blood, shortness of breath arising therefrom, and for all complaints caused by "CELL DISMEMBERMENT" of the blood.

Specially recommended also for all expectant and the nursing mothers.

PRICE 12/6 POSTAGE 3/6-

Beware of worthless IMITATIONS elsewhere
(MANUFACTURED IN FRANCE)

## Real Stockists:-

The Nigerian Medicine Stores, Tinubu Square Lagos.
Commercial Medicine Stores, Victoria Street, Lagos.
Alban Pharmacy Limited, Victoria Street, Lagos.
Yaro Depot, Broad Street Lagos.
Cosmopolitan Chemists Ebute Metta.
Ifeoluwa Medicine Stores 51, Bamgbose St, Lagos
Alders Pharmacy Patey Street, Ebuta Metta
Mrs C. O. Babajide Near Health Office Ibadan
Waterloo Medicine Stores (8, Palm Church Street, Lagos.(Phone 22878

AKIYESI:— Ri daju gbangba wipe sọbu ti wọn n'a o gbe ranşe lọra, bi bẹkọ awọn ẹlomiran yio fi ERU ilọta adamọdi tabi orişi omiran fun ọ ẹ, maşe gba rara.

**Waterloo Medicine Stores**
**8, PalmChurch Street P. O Box 333**
**Lagos Nigeria Phone 22878**

**Ati Pelu Ni Sobu Arabinrin:-**

MRS. C. O. BABAJIDE,
NEAR HEALTH OFFICE. IBADAN.

Bere ojulowo Egbogi omiran fun orişirişi amoci ti o ba fẹ ni sọbu awọn:—

## NJẸ O NI
# OTUTU IBA










DỌKITA SỌ WIPE




Da OTUTU IBA rẹ duro
gbe koro **"ASPRO"** meji mi
ARA RẸ YIO SI TUN YA-GAGA

# TANIMEHINOLA APA 46

**Lati Owo: J. O. SHOYINKA (Mushin)**

Tanimẹhinọla ko gbọrau, bẹni igbọran lẹbọ, o gun ori afara ti o duro kigbikigbi, o ni ha! ẹlẹya ni elegbe-de, eniti yio ti si inu ọgbun ainireti ni o nwa, pẹlu ofe susu lo ngori afara na lọ kemọ kemọ kemọ.

Nigbati o de arin meji afara, o ṣẹ mọ lẹse gbau, firiri po. o di isalẹ ọgbun bi Tanimẹhinọla ti re kan-na ni o fi igbe ta pe O o roo, aiye mi re o, o kan nja lọ doo, titi o fi de isalẹ ọgbun. O to wakati kan ki ooyi to ka loju rẹ. Nigbati ooyi ka tan, ni o to sẹse mọ ibiti on wa O ni ha! ibo ni mo wa yi o Olodumare? ki o to wi bayi ta, awọn Mọlẹ ti dahun wipe ilu awọn Enmọ lo de yi o. O woyika rairsirai, kosi ciyẹ iwaju paapa ko si ṣe lọ, ẹhin paapa ko si ṣe pada si, o tun bẹrẹsi se aroye, o ni ha! Iwọ Ọba Adẹda, ewo ni mo tun kan yi? bi mo ti wa iku to, bẹni iku nsa fun mi, eyi ti nba fi ha iku pade, iya ati iṣẹ ni mo nba pade nigbagbogbo, baba tun wo, ilu Enmọ ni mo tun de yi, ati tun yọ nihin nkọ?.

Ki o to pari aroye rẹ, oyẹ la wa too, ojumọ si mọ wa gboo. Eru ba Tani-mẹhinọla gidigidi nitoripe ko ti ẹda Ọlọrun kan, esinsin paapa ko ta firi, atẹgun paapa ko fẹ yẹu, gbogbo ilu na ri wutawu-ta. Nigbati o di wakati meji ti o ti joko ni awọn Erikitola su yọ bi ewe rumọ— ekida gbogbo wọn jẹ irunmolẹ, eyiti o nfi idi wọ nfidi wọ, awọn ti o nfi ori rin ko lonka, ọpọ sua lo nringe, ẹgbagbeje ni o nfaya wọ bi ejo oro pesi jẹ. Tanimẹhinọla ti gbagbe ara rẹ si iduro, ki o to yirapada, wọn ti kan lara.

Ohun ti o ya lẹnu ni pe nigbati awọn de ọdọ rẹ, ẹlukuluku duro lori ẹsẹ rẹ sansansan ni, aṣaju wọn ti orukọ rẹ njẹ ENMỌ gba Tanimẹhinọla ni eti araga kan, ki ṣe ti ẹnu didun, o digbo lulẹ, o si daku lọ kanrin.

Nigbati Enmọ tun fun ni igbati keji, ṣau ni o dide, oju rẹ si da wai. Ina njo a nfẹ kiamosa o ti kawọ sẹhin, o duro ṣan bi I ti ko farakan J. Enmọ ni kini o wa de ihin, nibo ni o si nlọ.

**AKIYESI:-** Ni ọ to nbọ lagbara Odua, ẹ o ma ka nipa esi ti Tanimẹhinọla fun Enmọ ati oro ti Enmọ sọ. Ẹnyin O kawe mi Tanimẹhinọla e bawo n'la iya— E ku ipalẹmọ Odun Keresimesi o.

Printed and Published by
Modupẹ Printing Press
16, Bamgbose St. Lagos
Olotu E. A. ADENIJI
51, Tẹjuosho Street
Suru-Lere Yaba.

# Otelemuyen nki nyin o

Mo dupẹ lọwọ ẹnyin onkawe Irohin Imọlẹ ti ẹ nkọwe si Ọgbẹni Shoyinka Oni tan alarinrin ti ẹ si nbere emi Ọtẹlẹmuyẹn pe kinise ti nko fi sọrọ sinu Irohin Imọlẹ mọ lasiko yi, gbogbo iwe nyin ni Ọgbẹni Shoyinka fi njiṣẹ, Oluwa Alanu ko ni ko airoju raye ba yin nile aiye yin Aṣẹ. Igbokegbodo mi ni ko ti jẹki ẹ ma gburo mi lati ọjọ yi, ṣugbọn nisisiyi mo ti tun bẹrẹ o.

HA! ENMỌ O! WOLI ODI NRIRAN O SI NṢE IWOSAN

Ohunkohun ti emi Ọtẹlẹmuyẹn ba sọ, bẹẹ lo 'ri; ẹniti ko ba gba mi gbọ, ara rẹ lo ntan jẹ. O ta si mi leti finrin pe "WOLI ODI" ti ko gbọnran, ti ko si le sọrọ ṣẹṣẹ de si Mushin atipe o nṣiṣẹ Iwosan nipa ẸMI-MỌ, ohunkohun ti o ba si le ṣẹlẹ si enia lọjọ iwaju, o nri nioni ha! iṣẹ Ọlọrun ma poju, bawo ni Ọlọrun ṣe fi Ebun Agbara Emi mimọ yi jinki Odi? Mogbera sọ, mo fi ọna wẹlọ ki nto lede ile ibiti oti nṣe iwosan yi ki ntole raye ri o fẹrẹ to wakati kan, nitoripe nṣe ni enia bi ewe rumọ, ọpọlọpọ wa lati Kano Sokoto ati lati ọna jinjin rere lati gba Ore Ọfẹ Ọlọrun lati ọdọ Woli yi, Ẹniti ẹgun ba gun lẹṣẹ lo nse lankanlaka to alabẹ. Iwọ ti o nwa iwosan mujafara lati lọ ri WOLI ODI yi, "YIO SI RI FUN Ọ GẸGẸBI IGBAGBỌ RE"

Akiyesi:—Lọsẹ to nbọ ẹ o ma ka nipa Woli yi gẹgẹ-bi ẹ ti ṣe le ba sọrọ ti yio si gbọ ati ibugbe rẹ

Ọtẹlẹmuyẹn wi tirẹ o ẹniti o ba ni eti lati fi gbọ ki o gbọ.

